Bibeli fun awon omode

# Danieli Igbekun



Akosile lati owo: Edward Hughes

Ayaworan: Jonathan Hay
Alastair Paterson

Olu'lo: Mary-Anne S.

Atunmo ede: Oluwashina Oluwadimu

Alakoso: Bible for Children
www.M1914.org

©2023 Bible for Children, Inc.
Iwe ase: Oni ase lati se atunko tabi attune itan yi,
niwon igba ti o ko so di owo.

Danieli pelu awon ore meta re n gbe ni Israeli.  Lojo kan oba nla kan wa si ilu abinibi won, o si ko gbogbo awon okunrin abarapa won lo si ilu tire.  Oba yii ni oruko to gun - Nekadine sari - o si n gbe ni ilu to jina rere Babiloni.



Won n se itoju awon odokunrin daradara ni Babiloni.  Oba yan awon odomokunrin to jafafa to si dara ju lati gbogbo orile-ede agbaye.  O pinnu lati ko won ni ede Babiloni ki won ba le di iranse ti yoo wulo fun ijoba re.



Ounje won pelu dara, Nitooto Awon odokunrin wonyii n je ounje ti Oba n je. Sugbon Daniel ati awon ore re ko fe je ounje yii, nitori a fi jin fun orisa won. Danieli ti pinnu pe oun ko ni se lodi si Olorun oun. Olorun Israeli ti pase fun awon eniyan re lati ma se ni ohunkohun se pelu awon orisa ati olorun eke.



Danieli bebe lowo eni to n se akoso ikekoo re pe ki O ma fun oun ni ounje oba, Bi oba ba gbo eyi, inu yoo bii, Sugbon, Olorun ti se ojurere fun Danieli lodo okunrin yin.



O gba lati se oun ti Danieli ati awon ore re beere. Fun ojo mewaa won n je efo ati omi nikan. Nigba ti o pe ojo mewaa Danieli ati awon ore re dun wo ju awon to n je ounje oba. Eyi mu ki a gba awon Danieli laye lati tesiwaju ni jije efo ati omi.



Awon Okunrin yii bu ola fun Olorun, Olorun paapaa bu ola fun won, Olorun fi ogbon ati oye itayo fun won ninu gbogbo ohun ti won n ko wonati pe Danieli ni oye lati mo gbogbo iran ati awon ala.



Leyin odun meta ikekoo ni Babiloni, a ko gbogbo odomokunrin to Oba Nebukadinesari wa. O yan Danieli ati awon ore meteta gege bi eni titayo laarin gbogbo won. Ni tooto, oba ri pe Danieli ni oye to tayo ju ti gbogbo awon ologbon ijoba re lo.



Lasaale kan, Oba la ala to buru. O pe awon opidan re, awon aworawo ati awon alafose. Oba wi pe mo la ala kan, “okan mi se n se aniyan lati moye ala naa.” Awon ologbon naa dahun pe “ki oba ki o pe! So ala naa fun awon iranse re, awa o si so itumo re fun O.”



Oba dahun, "Rara! E gbodo so ala ti mo la ati itumo re. Ti e ko ba so a o ke yin wewe a o si fi ina sun awon ile yin! Sugbon bi e ba so ala naa ati itumo re," Oba te siwaju, "e o gba ebun, iree ati ola" ko si eyikeyi ninu awon amoye ti o le ro ala oba.



Awon amoye oba wi fun oba pe, “ko si eda eniyan kan lori ile alaye ti o le se ohun ti oba n beere. Awon olorun keekee lo le se eyi, won ko si gbe ori ile inu bi oba gidigidi.” Oba kede “E pa gbogbo awon amoye Babiloni run!”



Nigba ti awon ologun wa mu Danieli, o wi fun Arioch, Olori ogun oba, ki lo de ti Oba n pa awon amoye? Nigba naa ni Arioch so ohun gbogbo ti o sele fun Danieli. Danieli lo lati ri Oba, o ni ki oba fi akoko fun oun, pe oun yoo so itumo ala re fun.



Nigba naa, ni Danieli pada si ile re, o si so ohun gbogbo fun awon ore re Sadiraki, Mesaki ati Abedinigo. Danieli ko mo ala naa tabi itumo re sugbon o mo enikan ti o mo ohun gbogbo. Eni naa ni Olorun. Danieli ati awon ore re gba adura.



Olorun fi ala naa ati itumo re han fun Danieli. Danieli fi ibukun fun Olorun orun, o wi pe “ibukun fun oruko Oluwa titi lailai nitori ogbon, oye ati ipa je tire.” Danieli yara to oba lo, o wi fun pe “Olorun kan wa ni orun to n fi asiri han” o so ala ati itumo ala naa fun oba.



Nigba ti oba Nebukadinesari gbo ala ati itumo re, O wole fun Danieli o wi pe, “Olorun re ni Olorun awon Olorun Oluwa awon oba, eni ti o n fi asiri han, niwon igba ti o le tu asiri yii!” Nigba naa ni oba gbe Danieli ga, o si fun ni opo ebun, o fi se alakaso lori gbogbo ekun Babiloni, ati alabojuto awon amoye Babiloni.



Danieli Igbekun

Itan lati inu oro Olorun, Bibeli

lari ka ninu

Danieli ori kinni ati Ikeji

"Iwole oro re funwa ni imole."
Orin Dafidi Ori kokandinlogofa ese adoje

Opin

Itan Bibeli yii so fun wa nipa Olorun
iyanu wa t'oda wa ti osi fe ki amo ohun.

Olorun mo wipe ati se ohun ibi, ti ope ni ese. Iku ni ere ese, sugbon Olorun feran re tobe ge tofi omo re kan soso, Jesu, ranse lati ku lori igi agbelebu ki osi jiya fun ese re. Jesu si pada wa si aaye osi losi ile l'orun! Bi o ba gbagbo ninu Jesu ti osi toro idariji ese re, Yi o se eyi! Yi o si wa gbe ninu re nisisiyi, iwo yio si gbe pelu re lailai.

Bi o ba gbagbo wipe otito ni eyi, so fun Olorun wipe:
Jesu mi owon, Mo gbagbo wipe ire ni Olorun, o di eniyan lati ku fun ese mi, osi wa laaye sibe. Jowo wa sinu aye mi ki osi dari ese mi jimi, ki emi ki oni aye otun nisisiyi, ati ni ojo kan ki emi kole wa pelu re titi lai. Ranmilowo lati gbo tire ati lati je omo o re. Amin.

Ka Bibeli re ki osi ba Olorun soro lojumo!
Johannu ori keta ese kerindinlogun.